NYC
Bill de Blasio
Mayor

Department of Consumer Affairs
Julie Menin
Commissioner

# OWÓ ÌSINMI ÀÌSÀN:
# OHUN TI AGBANISIṢẸ GBỌDỌ MỌ

Awọn oṣiṣẹ kan gbọdọ tele New York City's Earned Sick Time Act (Paid Sick Leave Law) (Agbekalẹ Akoko Sisan Aisan ti Ilu New York (Ofin Isan Isinmi Aisan) bẹẹrẹ lati April 1, 2014. Labẹ ofin yii, oṣiṣẹ to wa labẹ rẹ ni ẹtọ lati lo isinmi aisan fun abojuto ati itọju ara wọn ati ẹbi wọn.

Ẹka Ìṣe Alajẹtan (DCA) pese iwe yii lati ṣe itọni fun agbanisiṣẹ nipa ojuṣe wọn labẹ ofin. DCA yoo ṣatunto iwe yii bi o ti yẹ. Jọwọ kiyesi awọn deeti labẹ iwe naa. Lati ka ofin ati awọn Ibeere Oreekoore nipa ofin naa, lọsi **nyc.gov/PaidSickLeave**.

## AGBANISIṢẸ GBỌDỌ PESE ISINMI AISAN

| Iye awọn Oṣiṣẹ | Iye Isinmi Aisan ni Ọdun Kan | Isinmi Aisan ti a San tabi ti a ko San | Iye Sisan |
|---|---|---|---|
| 5 tabi ju bẹẹ<br><br>*Gbọdọ ṣiṣẹ wakati ju 80+ lọ lọdun kan** | De wakati 40 | San | Iye sisan wakati ṣugbọn ti ko din ni $8 ni wakati kan (owo ọya to kereju) |
| 1-4<br><br>*Gbọdọ ṣiṣẹ wakati ju 80+ lọ lọdun kan* | De wakati 40 | Aisan | Koni ibamu |
| 1 tabi ju oṣiṣẹ agbegbe<br><br>*Gbọdọ ṣiṣẹ wakati ju 80+ lọ lọdun kan ki a si ti gba siṣẹ o keere ọdun kan lati ọdọ agbanisiṣẹ kanna* | Ojọ 2 | San | Iye sisan wakati ṣugbọn ti ko din ni $8 ni wakati kan (owo ọya to kereju) |

*Kiyesi: ''Ọdun kan" tunmọ si eyikeyi tabi ṣiṣẹntẹle akoko oṣu 12 ti agbanisiṣẹ pinnu.

***Kiyesi:*** Bi o ba ni akanṣe akoso ti o faye gba oṣiṣẹ rẹ lati lo isinmi aisan, akanṣe akoso rẹ gbọdọ nibamu tabi ki o ju agbekalẹ ofin lọ.

## AGBANISIṢẸ TI OṢIṢẸ RẸ KOSI LABẸ OFIN YII

Ofin yii ko dabobo oṣiṣẹ ti iṣẹ rẹjẹ ọgọrin wakati tabi din ni ọdun kan; akẹẹkọ labẹ eto iṣẹ gbogboogbo; oṣiṣẹ ti a nṣe ẹdinwo iṣẹ rẹ nipa eto ẹda-ẹkọ; oṣiṣẹ ile iṣẹ ijọba; oluwosan aisan ara, aisan ipalara, oluwosan ede, oluwosan eti ti o ni iwe aṣẹ lati ọdọ New York State Department of Education (Ẹka Ẹkọ Ipinlẹ New York) ti o wa ṣiṣẹ ni ẹda inu wọn, ti o pinnu akoko iṣẹ ara wọn, ni ẹtọ lati kọ tabi gba iṣẹkiṣẹ ti a fun wọn, ti a si nsan owo ọya wakati fun, ti o ju idamẹrin owo ọya gbogboogbo lọ; Alagbaṣe aladani ti ko ni ibamu pẹlu itunmọ labẹ New York State Labor Law (ofin Iṣẹ Ipinlẹ New York); olukopa labẹ Eto Iriri Iṣẹ; awọn oṣiṣẹkan ti o wa labẹ ifimọṣọkan idunadura kan. Niti ifimọṣọkan idunadura, oṣiṣẹ o si labẹ ofin naa bi ifimọṣọkan baya ipese ofin sọtọ ti o si ṣeto ipese anfani. Ṣugbọn, fun oṣiṣẹ ni ẹka ikọle tabi ile iṣẹ ohun itaja ti o wa labẹ apapọ ifimọṣọkan idunadura, ofin ko kan wọn bi ifimọṣọkan baya ipese ofin sọtọ. Fun itọni lori apapọ ifimọṣọkan idunadura, ka Ibeere Orekoore ni **nyc.gov/PaidSickLeave**.

## AKIYESI ẸTỌ OṢIṢẸ

| Oṣiṣẹ | Deeti Ti a Kọ Akiyesi toto Fun Oṣiṣẹ |
|---|---|
| Titun<br>*Akọkọ gba ni tabi lẹhin 1,oṣu igbe 2014* | Akoko akọkọ ti a gbani siṣẹ |
| Ti o wa<br>*Ti n ṣiṣẹ fun agbanisiṣẹ ṣaaju 1,oṣu igbe 2014* | 1, oṣu ebibi, 2014 |

O gbọdọ ṣeto akiyesi akọsilẹ fun oṣiṣẹ kọọkan niti ẹtọ isinmi aisan oṣiṣẹ, eyi ti isinmi aisan ti o tọ ati lilo wa, ẹtọ lati ṣe ipẹjọ, ati ẹtọ lati bọ kuro ninu igbẹsan. Akiyesi naa gbọdọ sọ ọdun kan rẹ, pẹlu Deeti Ibẹẹrẹ ati Deeti Ipari. Oṣiṣẹ ni ẹtọ si akiyesi yi ni Gẹẹsi ati, bi o ba wa ni ayelujara DCA, ede wọn. Akiyesi naa wa ni nyc.gov/PaidSickLeave.

## ISINMI AISAN TI O TỌ ATI LILO – DEETI PATAKI

| | Iye ti o Tọ | Deeti ti eyi ti o Tọ Bẹẹrẹ | Deeti Ti Isinmi Aisan wa Fun Lilo |
|---|---|---|---|
| **Oṣiṣẹ** | Wakati 1 fun gbogbo wakati 30 iṣẹ | 1, oṣu igbe, 2014 *(Oṣiṣẹ ti o ti wa)* | 30,oṣu agẹmọ, 2014 *(Oṣiṣẹ ti o ti wa)* |
| | | Ọjọ akọkọ ti a gbani siṣẹ *(Oṣiṣẹ titun)* | 120 ọjọ lẹhin ti a gbani siṣẹ *(Oṣiṣẹ titun)* |
| **Oṣiṣẹ Agbègbè** | Ọjọ 2 lẹhin ọdun 1 lẹnu iṣẹ | DCA yoo pese itọni ni nyc.gov/PaidSickLeave | DCA yoo pese itọni ni nyc.gov/PaidSickLeave |

*Imukuro:* Bi oṣiṣẹ ba ni aabo ifohunṣọkan akojọpọ idunadura ti o bẹrẹ ni 1, oṣu igbe 2014, oṣiṣẹ ti bẹrẹ sini ni labẹ ofin Ilu lati ọjọ ti ifohunṣokan tan.

## AKỌSILẸ IWE

O gbọdọ ni ki o si maa tọju iwe akọsilẹ ni ibamu pẹlu ofin fun o keere ọdun mẹta. O gbọdọ ṣafipamọ iwifun nipa ilera ayafi bi oṣiṣẹ ba fun ọ laye lati ṣafihan rẹ tabi bi ofin ba ni ki o ṣafihan rẹ. O gbọdọ le ṣafihan akọsilẹ naa fun DCA ni akiyesi ni ọjọ ti ẹ ba fi ẹnu ko.

## AKIYESI ṢAAJU

Bi a ba ti ri idi ṣaaju, o le beere fun akiyesi ṣaaju fun bi ọjọ meje fun idi ti oṣiṣẹ fi nilo isinmi aisan. Bi a ko ba ri idi ṣaaju, o leni ki oṣiṣẹ pese idi paato (reasonable) isinmi aisan (botitọ).

## AKỌSILẸ

O le beere fun iwe akọsilẹ lati ọdọ olupese iṣẹ ilera ti o niwe ẹri bi o ba lo ju ọjọ iṣẹ mẹta lọ gẹgẹbi isinmi aisan. Paid Sick Leave Law (Ofin Isanwo Isinmi Aisan) ko faye gba ọ lati maa bere fun irufẹ aisan lọwọ olupese iṣẹ ilera fun isinmi aisan. Iṣafihan ni ofin gbọdọ fọwọsi. O le ni ki oṣiṣẹ pese akọsilẹ ijẹri pe oṣiṣẹ lo isinmi aisan fun idi Pataki rẹ.

## ISINMI AISAN TI A KO LO

Oṣiṣẹ le sun isinmi aisan rẹ bi wakati 40 si ọdun keji. Ṣugbọn, ole fun oṣiṣẹ laye isinmi aisan wakati 40 ninu ọdun kan. O le yan - ṣugbọn ko pọn dandan - lati sanwo fun oṣiṣẹ fun isinmi aisan ti ko lo lẹhin ọdun kan. Oṣiṣẹ kole sun isinmi aisan wọn si ọdun keji bi o ba sanwo fun wọn fun isinmi aisan ti wọn ko lo ATI ki o pese iye owo fun isinmi aisan ti o ni ibamu tabi ti o kọja agbekalẹ ofin fun ọdun titun ni ọjọ akọkọ ọdun titun.

## IGBẸSAN

O kole gbẹsan nitori oṣiṣẹ beere tabi o lo isinmi aisan. Igbẹsan ni idunkoko mọni, ijiya, igbaṣẹ lọwọ ẹni, wiwo, idaduro fun igba diẹ, tabi iyọkuro ninu wakati rẹ, tabi awọn iwa ilodisi igbanisiṣẹ fun lilo tabi bibeere fun ẹtọ labẹ ofin.

## IPẸJỌ

Bi oṣiṣẹ ṣe ipẹjọ lọdọ DCA, DCA yoo kansi ọ nipasẹ meeli fun eredi akọsilẹ. O gbọdọ da DCA lohun laarin 30 ọjọ. DCA yoo ṣiṣẹ pẹlu rẹ ati oṣiṣẹ lati yanju ipẹjọ. A o tun ṣe iranwọ lati fohunṣọkan.

## AKIYESI IDẸJA

Bi o ba gba akiyesi idẹja, wa ni anfaani lati yanju idẹja lai pẹjọ tabi ki o farahan niwaju adajọ ti kii sojuṣaju ni DCA's Adjudication Tribunal (Ijoko Ipẹjọ DCA).

*Akiyesi:* Gbogbo agbanisiṣẹ gbọdọ tele ofiin yii bẹẹrẹ lati 1, oṣu igbe 2014. Titi di 1, oṣu ọwẹwẹ, 2014, awọn agbanisiṣẹ wọnyi yoo ni anfaani lati tẹle ofin laisi ijiya, ati idẹja ṣaaju 1, oṣu ọwẹwẹ, 2014 ni a koni lo lodi si agbanisiṣẹ yii:

- Agbanisiṣẹ ti o ni laarin 1 si 19 oṣiṣẹ
- Awọn okowo ti o nṣe nnkan ti a kọsi ipele 31, 32, tabi 33 ti U.S. Department of Labor's North American Industry Classification System (Ẹka U.S ti Iṣẹ Ile iṣẹ Ariwa Iṣe Iyasọtọ Amẹrika (NAICS). Fun akọsilẹ ẹkunrẹrẹ, lọsi http://www.bls.gov/oes/current/naics2_31-33.htm.

**Ibeere? O fẹ lọsi idanilẹkọ lati ni oye ofin?**

Pe 311 (212-NEW-YORK yatọsi NYC) Ki o beere fun iwifun nipa Isinmi Aisan Sisan.